# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead

Vol. V. No. 246 SATURDAY, OCTOBER 29, 1927. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

2 NOV. 1927


## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

Victor White, Esq., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

Price: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

## EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.

"AWA O MA JO, AWA O MA YQ, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wonyi dara fun akękęvęyę pupo, fun Igbeyawo Wolimo, Ijo-Qdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ęgbę, ati orişirişi ohun ayo miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATORO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

*Office* :—
No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

Coffins to suit your Taste.

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

# Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKĘ Onişowo "Gbabiogede" nta Panu-kikǫle ati kikanǫkǫ, Işo lorişirişi, Kokǫrǫ (Işika) t'ilękun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalǫwǫ, Simęnti, Qda lorişirişi ati Epo-ǫda, Fikifiki, Okun ęrǫ, ati Qşan, ati Pakun ti Awo-ęja lorişirişi, Awo ti awǫn Aganyin fi nko Ęja-şawa Tokun ati Ęja Abǫmafǫ, ni Şǫbu rę ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamǫ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işę Agbędę Iworo ati Fadaka.

Owo Qja rę fanimǫra. Ę lǫ ra tiyin nibę.

Are you a Mechanic ?—If so you must want Tools, now or soon!

Do you intend to put up a house ?— Then you will require Builder's Hardware!

In either case you cannot do better than call at

**B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores**

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

**J. C. VAUGHAN**

Ti ile-ǫja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ǫja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikǫ 'le fun tita ni owo-ǫpǫku-ǫyǫku.

Ilękun awǫn ile-owo mejeji wǫnyi şi silę fun awǫn Qmǫle ati awǫn Gbęnagbęna: bi o fę awo ni o, ero-ija dida'wo Ęo ni ję ǫ ni'ya ti o ba lǫ nibę:

Alagbędę Wura tabi ti Fadaka ni ǫ ni o, ęni l'oşe fun ǫ lati ra irin-işę tirę nibę ba ...

Owo Ogbeni J. C. Vaughan ti di Owo Ajanaku lǫjǫ to ti pę: bi Qgędę si ni Owo rę kakiri ibikibi. Agbę ni ǫ kai! bi o ri orişirişi ti o ri ra nibę ha yio şe ǫ.

Sure tete iwǫ Qmǫle, iwǫ Gbęnagbęna, Aranbata, iwǫ Asenję iwǫ Ageginigbo (Sawyer), Alagbędę Wura, iwǫ Alagbędę Fadaka, iwǫ ... re ba ori're tirę pade nibę.

Owo-lǫwǫ ni gbogbo ǫja meremere ibę.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RE

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

EMI NI IFA FỌ O?

A gbọn si ni leti pe awọn Oyinbo Onisẹ Ọba kan lọ ṣe Ipade Igbimọ Ibuwole nkan (*Assessment Committee*) ni Agege ni *Monday* ọsẹ yi: dajudaju irufẹ ipade bẹ ko ni ṣai jẹmọ Owo Asingba ti Ijọba nfẹ gba lọwọ wa nibi bi a fẹ bi a kọ. bawo ni ẹnyin Igbimọ yi ti j'ọgẹdẹ Ibuwole na si o?

ALAJOTA, RỌRA JO, ARA D'AWỌ.

Ninu ojo irọlẹ *Sunday* to kọja nda tabi koi da ni a ṣalabapode awọn igiripa-kọnrin ara oke mẹrin kan ni apa ebute Ẹlẹfun ti awọn nbu ijo mọra lakọlakọ ti nwọn si alagun bọyọ bi afegboludo, ti nwọn si nta ilẹ nipa wọnin, b'o ri bi awọn ero 'woran ti nwọn bo wọn, o dabi ẹnipe awọn alairi-kan-ṣe-kan kan ni nwọn jẹ yo tan ti nwọn si yi ara silẹ ninu otutu ebute Ẹpẹtẹdo lai ri ẹnikan fi kọbọ aladọjọ lọ wọ; igbe "owo mbẹ lẹsẹ odo" ijọ kini ko ri bi ba si mọ; lai si aniani oju npọn oro, o npọn ẹnit' o rọ. Ode oni ko jẹ bẹ, ọran awo ma ro f'ọgbọn ni.

---

FUN MI NG KO FUN Ọ, A KO LE JIJA ILẸKẸ DE ỌYỌ.

APA KEJI.

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Ajẹku ọrọ wa Satide ijẹjọ ni wipe, nigbati a ni Ọba yi bere lọwọ awọn Awo rẹ iyoku tan wipe ṣe ko tun si awo kankan mọ ti yio wa difa lori ohun ti a ni o gbe silẹ na mọ ti nwọn si sọfun wipe afi Awo kekere kan lo tun ku.

O si ni ki nwọn lọ pe awo kekere na wa ki on ri, itumọ ohun ti nwọn npe ni Awo ni Babalawo.

Nigbati Awo kekere yi de, ninu awọn Babalawo ti nwọn ti ki ifa si igba-ademu ti ọba yi gbe ka'lẹ ti nwọn ko si le mọ, nwọn nwo ẹnu ilẹ, nwọn nwo ẹnu ọkọ, nwọn nwo oju ara wọn, nwọn nṣẹ ara wọn lekanna ẹhin lati ri ẹlẹya Awo kekere yi, wipe nigbati awọn ko tete mọ ohun ti Ọba gbe si iwaju wọn eyi kekere yi ni yio wa mọ ọ.

Kekere awo de o fi ori balẹ fun Ọba, ati fun gbogbo awọn Babalawo wọnni, o si bere orukọ Odu-Ifa ti o fu, a si sorukọ rẹ fun, nigbati kekere awo yi ma dahun para, o ni, "Ha! kini oba ni on yio ṣe yi? Ki Ọba ki o yara wipe on ko ṣe bẹ mọ arara, ki o yara gbe ẹgbẹgbawa fun gbogbo awọn awo ti o pe jọ yi."

Ọba ni kilo faru rẹ? Nigbana ni kekere awo dahun, o ni "Emi kekere awo ki isi nile aiye, li o difa fun ẹnyin babalawo afide-jẹgbẹdẹ ti nwọn fi f'obira jiwẹnẹ, ti Ọlọfin yio de igba iwọ (Calabash's poison) fun ti nwọn ki yio le ki Ifa ṣi i."

Ọba dide fu, o ke "Ha"! Ṣugbọn kekere awo garun nibiti o gbe joko si; o wo oju ọpọn ifa, o ni, "kini ọba ni on yio ṣe ndan? Ki ọba yara mu ọgọrin igbin lọ bọ Odu ki o si yara fi eware mẹrindin-logun bọ Ifa, ki ọran buruku maṣe ti ọwọ ọba ṣẹ."

Ọba tun dahun pe "Etiṣe!" nigbana ni kekere awo dahun, o ni, "Fun mi, ng ko fun ọ, a kole jija ilẹkẹ de Ọyọ, ki a de ile Ọlọfin, bi a ba ti ni ija ikọkọ ri, lọjọ ti a ba de ile ọba, li a nsọ otitọ.

A da fun iwọ ọba ti a gbe ilẹkẹ wa fun pamọ, ti iwọ ọba ṣetan, ti o ni iwọ yio fi majele fun ọmọ ti o wa gbe ilẹkẹ na fun ọ pamọ jẹ ki ilẹkẹ na le jẹ tirẹ, nitorina ki iwọ ọba fun ọmọ onilẹkẹ ni ilẹkẹ rẹ, nitori egungun ni ti o ba jẹ yio ha ọ lọrun, ọran ilẹkẹ ki itan bọrọ, itumọ ede yi ni pe, ọran na ṣi ma di oruku.

Ohun ti gbogbo awọn babalawo ti o ti ki ifa si kini ti oba gbe sile na titi, ti nwọn si mọ ọ ti, ni awo kekere yi wo jẹ.

Ki a ma dena pẹnu, nigbati ọba gbọ ohun ti kekere awọ wi bayi, idi rẹ ja, idi rẹ di omi, ọba na wa dide, o foribalẹ fun Ifa kekere awo, o wa bere wipe ewo ni on yio ṣe?

Kekere awo dahun o ni, bi iwọ ọba ba ni, ki o ma ku, ki o yara re imu ẹgba mẹrindin-logun wa, ki o si bọ ẹwu ti o wọ si ọrun gunwa yi wa le lori, ki awọn wundia meji ru u lo si ile ọdọ on, warawere ọba ti ṣe gbogbo nkan wọnyi lati ọjọ na ni, nwọn ti sọ kekere awo yi di oriṣa.

Ki iyẹn duro sibẹ, ninu pe ọba ṣi nṣe awọn wahala ọran yi lọwọ, ni tẹgbọn-taburo (awọn ọmọ onilẹkẹ yi) ki ija mọlẹ ni perewu, tobẹ ti nwọn nfẹ pa ara won toto totọlsi oran apo ilẹkẹ ti nwọn tẹku yi, nwọn tina bọ ile si, nwọn gun ara wọn lọbẹ danwo, kosi ohun ti o ku ti nwọn ko ṣe fun'ra—wọn tan—ija yi le tobẹ ti o fi jẹ ohun ti gbogbo ilu nilati ko wọn lọ sinu tubu oba yi kanna.

Ni ọjọ keji nigbati gbogbo ilu pejo tan, lati mọ ohun ti o fa sababi ti ija lile yi, awọn ọmọ mejeji na bẹ si ode lati ro ẹjọ.

Nigbati nwọn ma fi rojọ nkọ, nwọn tu ifun oni sode nipa ọran ilẹkẹ yi, bi awọn tiṣe ji gbe ninu ohun-ini baba awọn ti o ku, ti a sọ ni ọsẹ to kọja, lẹhin ti awọn ṣe apamọpamọ yi, o si wa di ogun ohun ti ẹnikan ni lati gbe pamọ wipe ole ji lọ.

Nigbati ọba gbọ bi nwọn tiṣe ro ẹjọ nipa ilẹkẹ yi, ẹnu ya gidigidi wipe aṣe ọran ilẹkẹ yi tilẹ ni ẹnu ri, njẹ bi ou ko ba ni ero lati pe awọn babalawo pe ki nwọn ki ifa si ọran ilẹkẹ yi ti on si ngbidanwo lati pa ọmọ ti o wa gbe ilẹkẹ pamọ fun on yi, njẹ bi aṣiri ilẹkẹ, iba tiṣe wa tu si gbangba janma re, ti o ba wa di ohun ti ao pe ọba kalẹ lati ro ẹjọ.

Ki iṣe wipe ọba yi nsọ bayi si gbangba, o nsọ si'kun ararẹ ni ki a ma fa ọrọ gun lọ titi, nwọn pin ilẹkẹ na fun tọtun tosi, bẹni ija wa mupo.

Ohun anfani ti a fẹ fayọ nidi ọrọ yi, o pọ pupọ, eyiti o jẹ wipe o le gba wa to oṣu kan, ti a ba ni ki a gbe ẹnu le ni sisọ ṣugbọn a ba bẹrẹ si isọ tun ẹnyin ọkawe nisinsiyi, gẹgẹbi o ti jẹ wipe, aye kosi fun wa tobẹ loni, bi Ọlọrun ba ṣọ wa di ọsẹ to mb ọlagbara Rẹ, ao jẹki ẹ bẹrẹsi gbadun rẹ.

Ṣugbọn ẹniti o ba mọ arafi kewu ninu nyin daradara, tabi ti o gbọ agbọye ọrọ, o le ti ma fi ọrọ yi ṣe ariya silẹ de wa di ijo mẹjọ, ohun pataki ti o julọ ni ede awọn hausa kan ti o ni "Ankuri Mọgani Dunia" itumo rẹ ni pe—Suru ni ogun aiye. Ṣugbọn fun mi ng ko fun ọ, a kole jija ilẹkẹ de ọyọ o.

Emi ni tiyin nitotọ,

KEKERE AWO.

### OLUSAKIN'S COLUMN.

#### Anonymous Donation by an American Philantropist.

FOR SCHOOL AT ATHENS.

NEW YORK—An anonymous American Philantropist has promised the American School of Classical Studies at Athens half a million pounds sterling needed for the excavation of the site of Agora in Athens—*Reuters*.

#### Arrivals by the R.M.S. "Abinsi."

The following were amongst the passengers who arrived in Lagos by the R.M.S. *Abinsi* last week Friday, the Honourable Mr. Eric O. Moore, B.L., and Dr. Magnus R. L. Macaulay, M.B., Ch.B. E k'abọ.

#### Congratulation.

We congratulate Mr. Samuel Ayodele Thomas, Law Student of the Inner Temple, who has recently passed the Intermediate Bachelor of Laws examination of the University of London.

#### Heavy down pour of Rain.

We have experienced heavy down pour of rains during the past two weeks much to the satisfaction of Agege and district planters. This, we hope, is an indication of plenty of crops and foodstuff this year.

#### A Divorce Case.

FOLARIN *versus* FOLARIN.

According to the *Nigerian Daily Times*:—Before Mr. Justice M. L. Tew, in the divorce suit pending between Mr. Nathaniel Adekunle Folarin (Petitioner) and his wife Mrs. Comfort Rẹmilẹkun Folarin (daughter of Mr. E. T. A. Johnson) with one Joseph as co-respondent, a motion was made on the 24th instant by Plaintiff's Counsel for leave to dispense with naming a co-respondent in the action.

Counsel submitted that they had not been able to find the address of the "man in the case" although they had a letter from the Respondent giving them only the name. They were denying paternity of the child with the Respondent and had proofs that the Petitioner had not lived with Respondent for over a year.

The Judge:—What about the Russell case?

In disallowing the motion, His Honour said he would allow the Petitioner to put in supplementary affidavit of reasons why a co-respondent should not be named.

#### A Civil action betwe n Miller Brothers, Plaintiff and Mr. S. O. Ogunmodede, Defendant.

In the Supreme Court of Nigeria, on Tuesday, the 18th October, 1927, before Justice P. B. Petrides, Samuel Ọlafunmilayọ Ogunmọdẹde, who was employed by Messrs. Miller Brothers, Ltd., as salesman for about months to answer a civil summon for shortage of £616 14. 10d., as he admitted the deficits through his Solicitor Mr. A. Desalu, judgment was entered against him and his wife, Elfrida Henrietta Aina Glover (daughter of the late Mr. H. O. Glover) who stood for him as surety for the £616 14. 10, with £9. 15. 0 costs.

#### Public Holiday.

His Excellency the Officer Administering the Government has been pleased to appoint Friday, the 11th day of November, 1927, (Armistice Day) to be kept as a public holiday throughout Nigeria.

**The Lagos November Assizes.**

The November Assizes in Lagos has been fixed to commence from Monday the 7th proximo.

**King's College Lagos.**

The Tenth Annual Sports in connection with King's College, Lagos, took place last Saturday, on the College grounds, at 4 p.m., and the Inter-Schools Relay Competition will take place this afternoon at the usual place at 5 p.m.

OLUŞAKIN.

---

## ỌRỌ AGBAYEWO FUN AWỌN OBIRIN

### APA KEJI.

[ LATI ỌWỌ ỌMỌ AWO ].

Si Oniwe-irohin "Eko Akete,"

Mo bẹrẹ foji o,

Gẹgẹ bi ẹyin ọkawe wa yio ti ri ninu wosika mi ti ijẹjọ, mo tun tọrọ gafara lọwọ yin lati tun ba mi fi oju ifẹ wo ti ọsẹ yi, ani şe ọranyan ni pe ki Obirin tẹriba fun ọkọ wọn ti a ba si ri Obirin kan ti o ngboju gangan gan si ọkọ rẹ nile, onjẹ egun moyan, ọna ayimoye lo wa fun Obirin lati leri ba fun, ọkọ rẹ, nigbati Ọbanjigi ti kalararẹ da aiye ti o si da Adam tan, Ti o wa ri pe o to ki On da Obirin fun Adam lati ba jẹ oluranlọwọ fun gẹgẹ bi awọn opitan omiran ti nsọ pe Adam fun ararẹ lo bere fun Oluran lọwọ ki Oluwa to ri pe o tọ o si yẹ ki o to wa da Obirin fun Adam lati jẹ oluranlọwọ fun, gẹgẹ bi a ti sọ ni ijẹjọ pe lara Ọkunrin lati da obirin, gẹgẹ bi ẹyin na ti mọ, şugbọn Oluwa ko fi mọ nibẹ nikan, ani a gbọ pe lẹhin ti o ti şişẹ sara Obirin tan o mu wa fun Adam lati so loruko, nibẹ ni Adam ti dahun o ni eyi ni egungun ninu egungun mi ati eran ninu ẹran ara mi obirin ni a o ma pe ọ nitoriti lara Ọkunrin ni a ti mu Obirin jade wa. Ẹ raye tabi ẹ ko raiye lode, ẹyin Obirin akọgba ti o jẹ pe ti ẹ ba ti we lawani yin tan eyi ti ẹ npe ni gele ti ẹ ko fẹ mọ ọkọ yin mọ, ewo ni ko ba to fun yin lati tẹriba fun Ọkunrin ninu gbogbo eyi ti a sọ sılẹ yi boya bo jẹ pe Adam ko bere oluranlọwọ boya Oluwa ko ba ti da Obirin saiye, ẹli lọrọ o. Ako sọ pe Oluwa jẹbi lati da Obirin saiye o, şugbọn aigboran yin lafi ngun yin loju. Ẹkeji kẹ Ọkunrin lo ro ori rẹ ko to fun yin loruko tẹ gba sori loni nitori gbogbo nkan wọnyi ani eyi to ma ro pe pupọ awọn ẹlẹgbẹ mi yio ri si, nitori pe o ma şemi lanu pupọ nigbati a ba nri awọn obirin ti wọn nfọ ọkọ wọn leti nile labi orişirişi iwa miran ti ko yẹ obirin lati şe, bi ko ba sipe kama lugi oyin ni a ko ba daruko ẹni pupọ fun yin, pataki ẹnikan ta mọ, tojẹ pe oruko rẹ yio tilẹ bulọti iwe wa yi fun anfani ẹlomiran bi a ba ni kadaruko rẹ şugbọn a mọ daju pe bi a ko tilẹ daruko iru ẹnibẹ wọn mọ ara wọn.

Bi a ba wadi ohun wọnyi boya kojupe aya nrin irinkurin, ọkọ rẹ sọ fun u o di ja, bẹni okan kolegun. Oluwa ko gbani lọwọ obirin buruku afọjẹ obirin mi wa, a ma şe agbere mọ ọkọ rẹ lara bayi, boya o di ẹjọ *ah!* ẹnyin Obirin oniwa kuwa, bi ọkọ ko sọrọ njẹ ata Ọkunrin yi ninu ẹni ninu ẹrun ko ha ni bi Obirin koleriran to ba nfu ọkọ rẹ jẹ. Aye a gba Obirin miran to bẹ a ma şe agbere ninu ile ọkọ rẹ nigbati iyẹn ba şe janjan lọ si ibi şe nitori ati jẹun aya yi. Ẹ gbọ bi Obirin kan ti wi fun ọkọ rẹ, nigba ti iyẹn sọ fun pe iwa agbere wọnyi ko dara o ni jẹkami Baba Ilagba yi. "*You are too Selfish*" nigbati ko ni *Selfish* nkọ, ta ni nba bọ aya yi ọrọ re o, ẹyin Obirin Eko o dọwọ yin bi ẹ ba ti şe igbesi aiye yin si, ẹo ba nibẹ, nigba kan ri, niwọn ọdun to kọja diẹ sẹhin, a ma ngbọ awọn Obi a ma sọ pe, bawo lẹhin Ọdọmọbirin yi ti ntete loyun bayi, a şe die lori yẹn, ẹ sa wo awọn to nbọ lẹhin wa pataki awọn ti wọn nkiri ọja bi Ọkunrin ko wa wọn awọn lo nwa Ọkunrin, bẹni a ye ke lojojumọ. Ẹ jọ Ẹ ma pe mo yabara tun lọ fẹnu kan ọrọ omiran, ọrọ lo lọ bẹ. Ani şe Oluwa ti pa laşẹ pe Ọkunrin ni yio ma se Olori Obirin bi oti wun ki Obirin na ni owo to, lẹhin ngba ti o ba si nba wọn ni ọkọ, tulasi ni ko tẹriba fun u. Njẹ mo tun biyin lẹkan si iru awọn ti wọn ko tuyi ọko wọn lorişirişi ọna tabi ti wọn tilẹ nşu ọkọ wọn lohun lasan njẹ egun moyan nitoripe o pa aşẹ Ọlọrun da tulasi ni pe kojiya rẹ, Oluwa yio si jẹ niya rẹ kin şe pe a nşepe fun yin o, oti rara a tẹ ki ẹ mọ işẹ yin nişẹ nipo kipo ti Oluwa ti pe Ọkunrin na si, ẹyin Ẹ gba ọro wọnyi yẹwo lati ijẹjọ ti a ti nderu le boya a le ri ẹniti yio fun wa nidi rẹ ninu awọn Obirin ti wọn nfi nri ọkọ wọn fin, to bẹ, ti wọn si gba loju, anfani kuro lara tọkotaya to tara wọn npa, to ngba arawọn loju. Obirin ki Obirin ti o ba şiwọ lu ọkọ rẹ jẹ egun moyan nitoripe â ko ran bẹ wọn ko si to bẹ ni ọnakọna si ni wọn ko fi to bẹ nitoripe ẹgbin ni obirin to rope, on le fi ọkọ on şe nkan kikan to wu on nipa ohun aiye, iru awọn eni bẹ ni wọn ko ni afori lode aiye nitoripe wọn ru ofin Ọlọrun. Ẹ gbọ bi Oluwa tikalarẹ ti wi o ni lọdọ ọkọ yin ni ki ifẹ yin ma fa si on ni ko si ma şe olori yin. Ọrọ wọnyi ti to fun Obirin bi ọkunrin ko tilẹ sọrọ mọ.

Ẹyin Obirin ẹ mọ işẹ yin nişẹ, Ẹ ronu piwada, ki ẹ ba le gbade iye. Ọrọ diẹ to fun ọmọ luwabi n i t o r i n a a o duro nihin fun ironupiwada yin. Bẹ şe re, ẹ o ba.

Emi ni tiyin nitotọ,

ỌMỌ AWO.

Chief Secretary's Office,
Nigeria.
Lagos, 20th October, 1927.

Sir,

Referring to my letter No. 01823/182 dated the 22nd of October, 1926, I am directed by the Officer Administering the Goverment to forward, for your information a copy of a telegram received from the Secretary of State regarding the observation of the ninth anniversary of the Armistice. In the case of Lagos at 11 a.m. on the 11th of November, two guns will be fired in rapid succession and it is His Majesty's desire that all subjects of the Empire should refrain from work, noise, and movement for the space of two minutes as an act of homage and respect toward the Dead. At the end of the period of silence a third gun will be fired.

2. I am to request that you will impress upon your readers the solemnity of this occasion, its purport and its cause and that you will use your influence with such of them as are employers that they may secure silence among those in their employ.

I have the honour to be,
Sir,
Your obedient Servant,
K. L. Hall.
*for Acting Chief Secretary to the Government.*

---

TELEGRAM

Secretary Of State, London, To Governor, Lagos.

Dated 12th October, 1927.

---

*12th October.* His Majesty has approved of arrangements for observance in this country of Amistice Day 11th November on the same lines as last year see my Circular despatch of 24th November 1926. Full permission is to be given to those holding War Medals and decorations awarded to deceased relatives to wear such medale on the right breast at Amistice day ceremonies.

Secretary of State for the Colonies.

## ẸSIN AKỌSIN NI AṢẸṢẸ DA AIYE.

4 Ni iṣẹdalẹ aiye, a ka ninu awọn iwe itan pe Ẹsin kan na ni gbogbo orilẹ aiye nsin, eyiti wọn npe ni "*Wisdom Religion*" ni ede oyinbo ti a le tumọ rẹ ni ede ilẹwa bayi "Ẹsin Ọgbọn" tabi (Imọ) eyiti ọkunrin ni ọjọgbọn ninu ẹkọ ti anpe orukọ rẹ ni "Phytagoras" itumọ bayi ni ede Oyinbo, "*The Gnosis of the knowledge of the things that are.*"—eyiti itumọ rẹ jẹ bayi ni ede wa "Imọ ohun timbẹ," wọn si mu ara wọn ni ọmọ iya ati baba kanna, nitoripe orisun kanna sa ni gbogbo aiye ti dide. Eyi ni Ọlọrun kan ṣoṣo ti nṣọ Ẹmi Aiyeraiye. Ẹsin yi si wa ni orilẹ aiye titi ki isin Igbagbọ to de aiye (*Christian Religion.*) Ẹsin imọ ohun ti mbẹ yi ti wa ni orilẹ-ede awọn kan ti anpe ni Atlantis, ati, ni ẹyin na, ni Asia Ẹsin yi tanka gbogbo ayie ti a mọ pe o wa ni igba atijọ; Iṣẹkubọ tabi ami ẹsin yi mbẹ ni Temples, (Ile Isin) lara awọn opo ati ọpọn oknta ti awọn ara ilu Babylon, Egypt, China, India, Persia, ati Mosopotamia titi di oni oloni, to bẹ ti ẹnikẹni si le ri awọn nkan wọnyi fun ara wọn. Ni ibẹrẹ isin yi awọn olukọni igbana jẹ awọn ọmọ Ọlọrun ti a ka ninu Genesis, lẹhin na awọn Sagos ti India, awọn Magians ti ilu Babylon ati Persia, awọn Woli ti Israel, awọn olori olukọni Egypt (Hierophant) ati awọn arihin ri ohun ọjọgbọn ninu ẹkọ ti Greece ati olukọni Jesu ti anpe Christi ati awọn ti a fi mọ awo ijinlẹ ti o wa ninu ẹsin na, ninu awọn ọmọ ẹyin rẹ ni ibẹrẹ isin igbagbọ. Gbogbo awọn ti ati ndarukọ wọnyi wa ọgbọn ati imọ yi nipa bibẹ Ọlọrun wọn mulẹ, ati nipa Ijọba lori ẹran ara wọn (*Flesh.*) Ṣugbọn nigbati aiye bẹrẹ si lọ siwaju ero awọn enia bẹrẹ si ipin yẹlẹ-yẹle, ti olukuluku fi mu ọna tiwọn fẹ lati ma fi sin Ọlọrun fun ara wọn. Bi ere enia ba sa ti ga to, bẹna si ni Ọlọrun rẹ nto ni oju rẹ. Ninu gbogbo awọn olukọni ti a ka ninu iwe yi, ako ri ọkan ti o kọ ... pe bi Iya, Baba, Ọmọ, Ọkọ, tabi Aya ba ku ... ma wọ aṣọ dudu kasi ma kita, tabi Ije. Be... Koran tabi Bibeli kokọ ni, ni nkan wọnyi.

5. Emi yio gbidanwo lati tumọ iredi aṣọ dudu ti a nwọ bi oku baku fun wa ati iredi ohun ti o ... ki awọn Keferi' ma kita ati Ije oku wọn, ati ... runru awọn aṣa miran ti agba pẹlu ti kiṣe ti wa, ... ko si bawa mu rara ni ilẹwa.

6. Gbogbo wa, gẹgẹ bi onigbagbọ lati mọ ... Mimọ ni Ọlọrun—Ẹmi Aiyeraiye ṣi ni—Ko ... nṣe Ọlọrun okunkun—ati pe awọn enia ati ... abẹmi gbogbo ti Ọlọrun da si ode aiye ... Ọlọrun ni wọn nṣe—Nitori nigbati ẹmi ba lọ ... ni ara, nigbana ni ansọ pe enia ku. Bi o ... ireti wa ni pe bi ẹmi ba kuro ni ara—on pada ... Ọlọrun lọ—ati ara eyi ti nṣe ti erupẹ adi ... Erupẹ—bawo, lo ha ṣe tọ fun wa, lati ma fi ... dudu ṣe ọfọ oku—nigbati o jẹpe a gbagbọ pe ...

funfun lo tọ lati ma fi sin oku ti a si nṣe bẹ gẹgẹ. Ẹ gba eyi, ki ẹsin ro wo, fun ara yin.

## IṢỌFỌ OKU NI AṢA ILẸ WA.

7. Aṣọ arogbele tabi ẹwu awọgbele ti oku ba ku ba ni ara ẹni, on na ni afi nına nṣe ọfọ oku na—iba ṣe ọkunrin tabi obinrin, a ko gbọdọ wẹ, ẹni a ko gbọdọ fari tabi di irun wa—titi kan ekanna ọwọ ati ẹsẹ wa, a ko gb dọ re wọn—tobẹ aṣọ na a pọn fun en—Ni iru ipo eri ati ibanujẹ bayi la o wa titi oṣu mẹta fun okunrin ati oṣu marun fun obinrin, ti ao fi bọ aṣọ ọfọ na. Ale sọ pe iru ebu ti afi nbu ara ẹni bi, ede koyede diẹ ba wa larin wa pe—"Abori kikun bi ori ọlọfọ" jẹ eri si ohun ti aṣọ yi—iru ebu bayi sa şi wa larin wa ti afi nbu ara wa titi di oni oloni.

## IBỌṢỌ ỌFỌ OKU—NI AṢA ILẸ WA.

8. Nigbati ọjọ ti ao bọ aṣọ ọfọ na bato, nijọ na, ni ao fari tabi, di irun wa, ao re ekanna wa pelu, ao wẹ ara wa patapata, ao se onjẹ lọpọlọpọ nigbana ni ao ko gbogbo aṣọ ti ati nlo, lati fi ṣe ọfọ na lọ si iwaju Orişa wa, Oloye Orişa, eyi ti a npe ni Oni mọ gba" yio sin gba awọn aṣọ na lọwọ wa—asin sure fun olu ulu u wa ti ati nṣe ọfọ oku na, Nigbana ni ao berẹ si jo ti ao sin ma yọ. Lẹhin eyi la to pari isinku ati iṣọfọ ati ibọṣọ ọfọ oku wa na to ku, larin wa patapata—ti a ni igbagbọ pe oku na lọ kuro larin wa, bayi ni aṣa ilẹ wa nipa şiş fọ oku, ati ibọṣọ ọfọ oku. Ki şe nipa wiwọ aṣọ dudu kakiri, ki ẹnikẹni ba le mọ pe a nşe ọfọ oku wa to ku, eyiti o jẹ ede agabagebe julọ. Nitorina, ẹma jẹ ka tan ara wa jẹ—Bi a o je aşa Ilẹ wa ẹjẹ ki a tọwọ mu. Bi ao jẹ Aşa ka jẹ Aşa bi ao şe-Awodi ka şe Awodi.

---

## 20 Years Reminiscences in Nigeria.

By Hon'ble G. F. Tomlinson
*Secretary Native Affairs.*

---

Oyinbo ti a da 'rukọ rẹ si oke iwe yi şe asaro fun awọn Ẹgbẹ "Study Circle" ni ile Afari Ogun ni alẹ ijọ *Monday* ijọ kẹrinlelogun oşu yi. Awọn agbagba Eko lo wa lati fi eti gbọ irohin ohun ti oju Oyinbo yi ri lati ogun ọdun ti o ti de Nigeria. Diẹ ninu orukọ awọn agbagba ti o wa ni wọnyi.—Ọgbẹni Herbert Macaulay, Henry Carr, Dr. Jones, Ọbasa, Ọgbẹni Jackson, Cardoso, Lawyer Taylor.

Ọrọ ọna ilẹ Hausa lo sọ ju, o ni on ni anfani ati jẹ Ajẹlẹ lapa Bornu nigbati Ijọba Gẹsi fi fọ ibẹ, o si pitan lọ bi ilẹ bi ẹni, bi nwọn ti l'agbara to lisiko kan, o wa mu ẹnu kan *Native Administration* ni ipari ọrọ rẹ. O ni o yẹ ki a dimu dada, nitori nkan ilu wa ni, ki a ye sọ pe ibajẹ *(corruption)* pọ ninu rẹ, o ni *British Parliament* ti a ri yẹn, awọn ara ilu Gẹsi lo da silẹ fun 'ra wọn ti o fi da bi o ti ri loni. Lẹhin ti o sọrọ tan, o joko.

Olori awọn "Study Circle" wa bere bi ẹnikẹni fẹ bere ọrọ. Ọdomọde kan bere nipa Mahdi ti nwon ni o gbe ogun lọ si Bornu, Oyinbo yi si da lohun. Lẹhin eyi ni Ọgbẹni Macaulay wa sọro pe awọn dupẹ lọwọ Oyinbo yi fun ọro ti o sọ nipa ọrọ ọna ilẹ Hausa, o ni Oyinbo kan ti ko jẹ ki Oyinbo na ri itan ti a kọ silẹ nipa Ilẹ Yoruba ni ti Owo Ẹru ti o da ilẹ Yoruba ru, o ni a dupẹ pupọ lọwọ Ijọba Gẹsi fun Owo Ẹru ti nwọn parẹ, eyi ti o si ku ninu rẹ ni Onidajọ wa Petrides ti lọ lu mọlẹ ni Saro lenu ijọ melo yi O ni on fẹ bere ọrọ kan, ki Oyinbo na la fun ni dada, o ni awa Enia Dudu, a fẹ *Direct Native Rule* Ijọba ilẹ wa, nitoripe labẹ rẹ la bi wa, a fọ *Direct English Rule*, nitori labẹ rẹ la wa lati bi ọdun mẹrindiladọrin yi wa, şugbọn ewo ni Ijọba wa npe ni *Indirect Rule* ti nwọn nfi agbara di mọ wa lọrun yi (atẹwọ ho lọ kũ). Oyinbo dahun o ni Ọgbẹni Macaulay mọ ọrọ bere lati fi we enia lẹsẹ, o ni on ko ni le dahun ọrọ ti o bere yẹn o, Mimi sẹhin agbo ki nş'ojo.

Ọdọmọkọnrin kan tun sọrọ nipa ti *Native Administration*, bi o ti jẹ pe ki işe awa Enia Dudu lo nşe tarata, şugbọn awọn aieji lo pagi ti, nitorina ko le duro, o si yẹ ki a fa a tu. O ni on mu eyi wa ni imọran ni.

Lẹhin ti Oyinbo yi ti dahun ibere ọdomọkọnrin kan nipa ti owo *(trade)* larin ilẹ Hausa ati ti Yoruba ki relawe to de, Akọwe Ẹgbẹ "Study Circle" Ọgbẹni Akisanya şọpẹ lọwọ Oyinbo na fun ọrọ rẹ, ipade si pari.

FANOKUN.

## EKO AKETE

Eko, Saturday, October 29, 1927.

### A KO RI 'BI SA RE F'ỌRUN, ỌRUN BO NI BATAB TA.

Irufẹ ọrọ orin arofọ Aribiloṣo yi lo wa si iranti wa nigbati a gbọ pe Adele tabi Igbakeji Balẹ Ilu pẹlu awọn enia diẹ lọ si Agege ni *Monday* osẹ yi lati lọ la ti Owo Asingba *(Income Tax)* ti Ijọba npete lati gba lọwọ Eko ati agbegbe rẹ fun Balẹ Agege ati awọn enia ibẹ. A gbọ pe ninu ọrọ ti Ọgbẹni Oyinbo Findlay Igbakeji Balẹ Ilu Eko sọ, o wipe on papa ko mọ iye owo ti Ijọba yio bu ni sisan fun olukuluku enia ti o ni lati ma san owo yi lọdọdun, o ni ṣugbọn ọkan ni, o ni on tanma pe owo ti Ijọba yio bu na ki yio ni ẹnikẹni lara; talo le so pe ọrọ yi ko ri bẹ papa nigbati o ti ẹnu odidi Oyinbo onipo nla ninu iṣẹ Ọba King, bi Ọgbẹni Findlay jade, omi ti o ba ṣa ti ẹnu ẹja wa ni o ntutu ṣugbọn, a bere, ọrọ yi to tẹle daindain bi? A ko sọ pe a ko ka ọrọ Ọgbẹni Oyinbo na si, agbẹdọ! a ki gbọ buruku lẹnu Abọrẹ. Kini ko ni jẹ ki Ijọba fi kun owo sisan na lẹhin ọdun diẹ si; ẹnyin ilu ti gbagbe owo ti a nsan fun aja ni akọkọ bi? Ṣilẹ meji-abọ (2/6d.) fun gbigba iwe aja kọkan lọdọdun, ko fo fẹrẹ bi Lambẹ ko di ṣile mẹwa-mẹwa (10/-) fun iwe aja yi kanna lọdọdun bi? Ẹ tun wo ti owo omi: nisisiyi ẹrẹkẹ lo mọ pe iyọ dũn fun gbogbo awa ti a nsan owo yi; a ṣebi owo pọ̃ ni awọn Munisipa fi bẹrẹ gbigba rẹ nigbati nwọn fi nfi iye owo ti ile olukuluku to sinu iwe ti nwọn si fi nṣọwọ si awọn enia; nigbati o pẹ bi ọdun melo kan kọ ni awọn Munisipa kanna yi ja 'wu diju bi ilẹkẹ *rubber*, ti nwọn si tun bu kun owo omi ti o di sisan lode oni pẹlu karangida; ẹ tun wo owo ibode, a ṣebi awọn nkan miran ti nwọn ki ti ngba owo ibode lori wọn ri lo di gbigba owo ibode lori wọn loni; ngbọ, iwọ ti o fẹ ṣe Ganrandi ile rẹ; o ko mọ ẽlo lo mbọ nidi rẹ loni ki o to le jaja j'aja lati ṣe iwe na yọri bi? Iwọ ti o nlo otilẹ (*Postage Stage*) Ọba lati fi *post letter* si idalẹ bi England, kọbọ kọkan fun iwe *letter* kọkan ko fo lai di kọbọ meji-meji fun *letter* kọkan nisisiyi bi? Bi a ma rõ tabi bi a ma kọ̃ silẹ lọna bayi, ṣilẹ a kun ọna a bọ; idi rẹ niyẹn ti a fi Ijọba Gẹsi we ọrun, ti a ko ri 'bi sa re fun, ti o bo ni bàtàbàtà.

A sọ titi ẹnu fẹrẹ bo, a si fẹrẹ di alaṣeju loju awọn ẹlomiran, ni ti pe iyà ati inira nla ni Ijọba npete lati fun awọn enia nipa siso owo asingba *(Income Tax)* yi di gbigba; nigbati o jẹ pe owo ngbin kọ̃ lapo Ijọba, bi irọ ni bi otitọ ni, ẹ lọ wo Iwe-irohin Ijọba *(Nigeria Gazette)* ti ogunjọ oṣu yi (20 10 1927), nibẹ ni ẹ o gbe ri pe nigbati Adele Akapo Ijọba Nigeria, Ogbẹni Oyinbo A. H. Hodges ṣiro owo ti o wa ninu apo Ijọba tan, nigbati o si yọ gbogbo inawo tan, owo ti o ṣẹku silẹ ni 31st *July*, 1927, jẹ £5,850,722 10s. 11d. eyini ni ẹgbẹgbẹrun pọnun ọna ẹgbẹrun ọna marun o le ẹgbẹgbẹrun pọnun ọna adọta-le-lẹgbẹrin, ati ẹdẹgbẹrin pọnun o le pọnun mejilelogun, ṣile mẹwa ati kọbọ mokanla. Ẹnyin enia wa, ẹ ri ojũ aiye lode tabi ẹ ko rĩ, ki Ijọba ni owo tamtam bi iru eyi lapo tan ki o si tun ma ṣe wamọtipe gbigba owo asingba lori dukia ẹni lọdọdun igi ma da o! a ko sọ gbogbo ọrọ wọnyi lati fi ta Ijọba laiya, a ko to bẹ ṣugbọn ohun ti a nsọ ni pe owo asingba lori ṣiṛo ti Ijọba ngba nilẹ yi nfun Eko gbẹ, o si nmu inira ailefẹnuṣọ wa.

Lai si aniani, ẹnyin ilu yio ti gbọ pe owo asingba ti Ijọba la fun awọn ara Warri ati Sapele pe yio jẹ gbigba lọwọ wọn ti bi lẹ o si ti bi Adubi tobẹ ti ẹmi ẹnikan ninu awọn enia na ti bã rin nigbati a fi aṣẹ fun awọn Ọlọpa ki nwọn yinbọn fun awọn enia na, nigbati nwọn ko fẹ tuka lẹhin igbati a sọ pe Ijọba ti sọ fun wọn pe afara ki o ṣi wọn ku nibi ti nwọn wọ si, lẹhin igbati a sọ pe Adele Gomina ti ba wọn sọrọ tan; ẹ ṣ'ẹru ba ni, nitoto ẹniti o ju ni lọ lo nfi ọwọ gba ni loju. Irufẹ rukerudo ti o ṣẹlẹ ni Warri ati Sapẹlẹ yi ko ha mu ẹnikẹni ranti ija igboro ti o ṣẹlẹ ni Igberiko Saro

nkan bi ọdun 1898, nigbati Ijọba ibẹ fi da owo-ile gbigba silẹ; ẹ ko ha ranti fitafita ti Bai Bureh se nigbana, a ko sọ pe ki awọn enia wa ditẹ si Ijọba o, dede e; ṣugbọn ko si ofin ti o sọpe ki enia maṣe ke rara ti ofin kan ba nwọ awọn enia rẹ lorun; nigbati Bai Bureh ri pe ofin owo-ile gbigba na ni igberiko Saro yio wọ awọn enia on lọrun lo fi ke tantan bẹ, bi o tilẹ jẹ pe a ko ri si itiṣi ija ti o gbe si Ijọba Gesi nibẹ, ṣugbọn a woye pe gẹgẹ bi oye rẹ ti mọ lo ṣe nigba yẹn; ọrọ owo asingba yi kuro ni wàsá, atunbọtan Eko ṣa, ọwọ Ọlọrun lo wa.

A ko le ba ni tan, ki a fa ni ni'tan ya.

---

## ẸJỌ WO NI ISOBO TI NWỌN YIN NI IBỌN PA, ATI ẸNITI O YIN IBỌN PA A, NI SAPẸLI L'OṢU TO KỌJA LORI ROGBODIAN "OWO ORI", YIO RO FUN OLODUMARE L'ỌJỌ IDAJỌ?

[ LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU ]

Si Oni'we irohin "Eko Akete."

Mo bẹrẹ f'oji

Ibere nla ni ibere oke wosika yi, nitoripe ohun gbogbo ti enia ṣe l'aiye ni a gbọ pe yio jihin rẹ l'ọjọ Idajọ; eyi si ni gbòngbò ẹsin, tabi ipilẹ ti a kọ ile gbogbo ẹsin le l'ori, iba ṣe ẹsin igbagbọ, tabi ti Imale, tabi oniruru ẹsin miran l'aiye.

Iba ṣe pe aiye yi nikan ni opin tabi igbẹhin gbogbo Ẹda, laisi Ọlọrun ti ao jihin gbogbo iṣẹ wa l'aiye fun lẹhin ti a ba pa ipo da; ani, ti ko ba si ibẹru ibinu Ọlọrun, ọpọlọpọ enia ni ki ba ti bikita lati ṣe rere: iwa buruku, iwa janduku ni iba kun inu aiye fọfọ. Iwa talo ma mu mi ni olukuluku enia iba ma hu.

Ẹlomira le wipe, bi Ọlọrun ko tilẹ si, awọn Ọba aiye nkọ, awọn alagbara aiye nkọ, iya ti ẹlẹṣẹ yio jẹ l'ọdọ wọn nikan ti to. Bẹni. Ṣugbọn ẹṣẹ ti Ọba aiye tabi alagbara ninu aiye papa ba da nko? Tani le, ye! tani to lati ko esu rẹ fun wọn lẹhin Ọbangiji, Ọba a dakẹ da'jọ.

Ati jubẹ lọ, ti ko ba si ibẹru Ọlọrun, aiye ko le toro to bi o ti toro loni yi pẹlu gbogbo rukerudo inu rẹ; tani njẹ Ọba, tani njẹ alagbara? Ọga nla, ọga nla, ni gbogbo wa iba jẹ ninu aiye, apafọn ni a ba ma pa, ara wa lai bẹru ohunkonun, tabi ẹnikẹni.

Ṣe igbati a r'oju, ti a r'aye tan ni a nfi ẹnikan jẹ Ọba; iṣe kekere kọ si ni igbagbọ, tabi ibẹru Ọlọrun, ti ṣe ki aiye to le ni iba alafia ti o ni loni.

Kilo sọ awa Yoruba apa ihahin di obinrin, kilo—sọ wa di enia pẹlẹ bikoṣe igbagbọ, bikoṣe ibẹrun Ọlọrun?

Nigbati awọn Oyinbo Ojiṣẹ Ọlọrun kọko de arin wa ṣiwaju Ijọba, ẹkọ ti nwọn nkọ awọn baba nla wa npe "Ẹ ko ihamọra nyin danu, ibọn, ada, ati ọfa nyin. Ẹ ko gbogbo egbogi nyin danu, ati gbogbo nkan-ki-nkan ti ẹ fi nṣe agbara. Ẹ gbẹkẹle Ọlorun fun ohunkohun, ẹ ma gbadura si I fun ohunkohun ti ẹ ba nfẹ, yio si da a nyin lohun. Ẹ ko ofin mẹwa s'ori.

Ẹ ko gbẹdọ bọ oriṣa, ẹ ko gbẹdọ ja'le, ẹ ko gbọdọ pa enia, ẹ ko gbẹdọ jẹri eke, ẹ ko gbẹdọ ṣe agbere, ati ohun gbogbo miran ti ko dara. Ati jubẹ lọ, gbogbo iṣẹ nyin l'aiye lẹ o jihin rẹ l'ọjọ Idajọ.

Ọrọ Ọlọrun yi wọ awọn Baba wa l'okan tobẹ gẹ ti nwon fi fi ayọ ati itara nla da gbogbo nkan ti nwọn ti fi nṣe agbara ri nu. Ogun Afẹri, Agbelep'ọta, Egbé, Ogun Akọyà oniruru, Ogun miran ti a gbọ pe o le sọ odidi Ilu di ahoro, Epe, Afọṣẹ, Ayajọ, Ṣigidi, Mágun, Majele, ogun ti nwọn fi nja ogun ti ko njẹ ki ota ibọn ron Balogun tabi ada ri won gbe'ṣe; oniruru ogun miran tabi ogun buruku gbogbo ti awọn alagbara fi nṣe Ọla, gbogbo rẹ ni nwọn danu patapata, pẹlu ohun ija wọn miran bi ibọn, àdá, ọfa olóró. Bibeli ati Alukurani si di odi igbala wọn.

Nwon nkọrin bayi pe:—Ṣango, Ṣango, ko le gba ni o, Ọya, Ọya, ko le gba ni o, Jesu Olugbala mo f'ori fun, Jesu Olugbala mo f'ori fun, Tori nma bá ku gbe, ẹ jare!

Inu Imale papa ndun, nwọn nṣe aisun ọdun, nwọn ntan ina dini, nwon nfọ kiri wipe:—Anọbi ṣẹrẹ ina Ọlorun ko njo Ile. Igbagbọ ati ifẹ wọn po si Ọlọrun tobẹ gẹ ti nwon fi ni ero pe bi nwọn tilẹ ti "ina Ọlọrun" na ti nwọn mu dani bọ Ile, Ile ki yio jo.

Lona bayi ni awọn baba wa fi di obinrin patapata tabi majeṣi ti ko tun mọ ọwọ ọtun yatọ si ti osi mọ. Ani, bi ẹlomiran ninu wọn ṣaisan bayi, ko jẹ f'ẹnu kan egbogi, adura ṣa ni yio ma gba, yio si ma fi Bibeli tabi Alukurani ro'ri l'alẹ nitori ala k'ala. Omi lasan ti ladugbo nmu ku, ni alaisan miran ninu wọn nmu titi yio fi yoju si orun apapandodo pẹlu ayọ ati ifẹ lati ri Jesu. Nwọn ka gbogbo ohun aiye si asan ati omulẹmofe!

Ogún ẹmi Ọlorun ibẹru Ọlọrun, ati iwa pẹlẹ yi, ni nwọn si fi silẹ fun awa ọmọ wọn tobẹ ti pupọ ninu wa ko le ri ọbẹ ge ẹja n'ile lai tọrọ kiri adugbo, ki a ma ṣẹṣẹ sọ ti ibọn pẹlu ada.

Bi a ba dide ninu amodi, o di ọna ile Afa ni Ṣọṣi rẹrẹ lati fi owo dupẹ; bi iyawo bi'mọ, àgàgàgà Bi a ko ri iṣẹ ṣe, a nlọ tọrọ adura, bi a ri ṣe, a nlọ

fi owo dupe ; idamu ki damu, tabi wahala k wahala, to wu ki o ba wa ninu aiye, "Olorun lo fe be" ni ede wa.

Nigbati o ṣe, enia funfun kanna to mu esin Igbagbo pelu Bibeli wa fun wa nihin, nipa eyiti a tú gbogbo ihamora wa sile, enia funfun kanna yi tun mu "Ijoba" wa lehinna pelu "Ṣoja" ati oko ogun (*Army and Navy*) gege bi ihamora won.

Nwon gbe Bibeli—takada-fun wa lati fi ṣe agbara, awon papa mu idà ati obe dani, ibon ati agba, pelu Bibeli ti won.

Bibeli ni Ijoba ha lo fun awon ara Ijemo nijesi, Bibeli ni Ijoba ha lo ni Papalanto lakoko ogun Adubi, Bibeli ni nwon ha lo fun awon ara Isehin nijesi ; ani, Bibeli ni nwon ha fi pa Isobo ti o ku ni Sapeli ni ij kandinlogbon (*September 29th*) ni Sapeli nitori rogbodian "owo ori"? Bibeli ko ; bikoṣe Ibon, iru ihamora ija ti nwon ti je ki awa ko danu nitori ki a le de Ijoba Orun.

Boya ke, pupo ninu awon orile ede alawo funfun ni ko fe ba Enia Dudu gbe Ijoba orun po lo je ki nwon ma hu iwa ti o le so pupo ninu awon orile ede nwonyi di ero ina orun apadi, loju wa·

Ilu ké, ké, ké ; ilu yán, yán, yán, pe ki Ijoba wadi ohun to mu sabati ati so ara Ijemo di ero orun esan gbangban, nwon wadi nitoto, şugbon titi di oni, ni o fi dabi enipe Ijoba fi abere ran enu re ni aranpa sidi oro na. Ogun buru, ilu ko dún.

Oro nipase owo ori ha ko lo da ogun Adubi sile, kilo tun da rogbodian sile ni Warri, ni Sapeli, larin awon Isobo nisisiyi. Bi nkan ba nlo bayi, ninu ewu ha ko ni awa ara Eko papa wa, tabi enia melo ninu wa ni inu re dun si ajaga ofin "owo ori" ti Ijoba fe so mo wa lorun yi ninu wa, papa nigbati odá owo ko da Ijoba, ti Ijoba ko si ninu inira, ti owo tamutamu si seku si apo Ijoba lehin gbogbo inakuna.

Ni gbogbo aiye, orile ede wo lo nfi itara pelu ayo nla san iru owo ti Ijobo nfe gba lowo wa yi lakoko bere, papa lai nidi, bi a ko ti mo idi pataki ti Ijoba se fe gba iru owo be lowo wa nisisiyi, lai bikita rara fun oniruru gbogbo ona ti owo fi ngba lati owo wa de àjùlú Oba ?

A ha le ba Ijoba tan, ki o si fe fa wa ni itan ya bayi ?

Ni gbogbo Ilu *Nigeria*, a fere le wipe ko si Onişowo kan ti o to *Niger Company ;* eyi yio si je ki e mo bi owo ológbe Lord Leverhume ti po to ki o to le ra gbogbo òwò *Niger Company*, ati ti awon egbe Onişowo nla nla miran pelu. Şugbon pelu gbogbo re nko, àdánu nlá nlá ha ko ni Lord Leverhume pa. Opolopo Oyinbo Onişowo miran ha ko lo pa adanu pelu ? Egan ni he, àdánù kekere ko ni Ogbeni Peter J. C. Thomas pa ninu owo ; melo ko ka ninu Onişowo Enia Dudu ni ran ti "ate ileke" won lailai ti di "ate orunla" loni.

Ati obinrin ati okonrin, tani ko pa adanu lori òwò : ati akowe Oba, ati ti Onişowo, melo ninu won lo da ni ogorun ponwun pere ni ipamo ? Agbedo. Kaka be, pipele ni owo npele si i ni apo Ijoba, owo temi, owo tire

Gbogbo Ilu fere di okuta lan ; şugbon, sibesibe, o dabi enipe Ijoba fe lati fi ori kunkun fún omi jade lati inu apata. Ijoba nfe lati ré isun ti wa sinu ibú tire

Gege bi opolopo enia kakiri aiye, gege bi opolopo enia l'Eko ati ilu miran kakiri *Nigeria*, awon Isobo ko fe lati san owo asingba fun Ijoba, ko tile ye won rara bi Ijoba ti se ni lati ba won je "obe olokiti" won, lai ba won se "egunsi."

Ona ti Ijoba ro pe on ti fi ba won se egunsi, ati eyiti on yio tubo ma fi ba won s'egunsi si i, a gbo pe Ijoba la a fun won titi, şugbon ko ye won.

Awon Isobo pinnu, nwon si mu ipinnu na se, nipa alaiba Oyinbo ra oja koja ni Şaku ti nwon si si ilu won mo, nwon si so ipanpa lati maşe ta oja koja fun Oyinbo mo pelu.

Nkan nburu siwaju ati siwaju si i, ki iwe irohin ojojumo ti a npe ni *The Lagos Daily News* to gbe iku ta, to fi enu la ewu nla, to si kede re fun gbogbo Ilu gbo pe, Rere nun si awon ara Isobo iara ni Sapeli nitori rogbodian owo asingba ti Ijoba nfe gba.

Lehin ti iwe irohin yi, *The Lagos Daily News* ti koko hu iwa akoni nipa ki kede ibon ti Ijoba yin si awon Isobo ni Sapeli ni ijokondinlogbon, ni awon iwe irohin miran sese bere si pe oro na so diedie, ki Ijoba papa to ro ejo.

Nwon ni a gbo ejo enikan da, agba oşika ; a koi gbo—ti enu Isobo, Ijoba nikan lo si ro'jo, nitori na, o soro ki a to le fi ejo Ijoba nikan da Isobo l'ebi, tabi da won lare.

Şugbon kini e tle ri ejo ti Ijoba ro si ? Ibaşe pe Onidajo Kotu ni wa ni, ki enikeni ro iru ejo be niwaju wa, kiakia ni awa iba da eniti o fun won ni aşe lati yin ibon pa enia be l'ebi ; ti o ba si wipe idajo wa ko te on lorun, o le ro arotunro ejo (apili) niwaju Onidajo meta, ti nwon ba si da a lare ni Kotu won, o buşe ni yen. Awa ki yio si je Onidajo kini ti Kotu Onidajo meta koko tako idajo re.

Loju ti wa, ati ni ero ti wa, o dabi enipe inu fùfù ati ori kunkun nyo Ijoba lenu nigba miran ; a si tanma pe bi Ijoba ba fi ele ati suru gbe oro na, boya isele nla ti o se ni Sapeli ni lolovi ki ba ti se rara ; anu si se wa pupo pupo lati wipe Ijoba fi aye sile fun enia pupo lati yo şuti si ogbon ori, ati lakaye, Ol la F. M. Baddeley, Adele Gomina, nigbati o wipe loju ti on, "nigbati awon Olopa sun kan ogiri ni nwon to yin'bon si awon Isobo, ati pe bi o sepe won ko yin ibon be, a ki ba ti ri enu so obun buruku ti iba sele."

Ijọba le jare l'oju ara rẹ lati yin ibọn, nwọn le jare loju ẹlomiran lati yin ibọn ; bi nwọn le jare bakanna lọdọ Olodumare nigbati nwọn ba ro ẹjọ, iyẹn ni awa ko mọ ; ṣugbọn loju ti wa, nwọn ko jare lati yin ibọn pa Isobo ti o ku.

Idajọ wa le ṣai tọ suna, nitoripe awa ki nṣe Lọya, awa ki nṣe Onidajọ, awa ki nṣe Ọlọrun.

Ẹjọ ti Ijọba ro ni eyi, nigbati a yi si ede Yoruba ; nwọn ni :—

"O pẹ diẹ nisisiyi ti awọn ti nri apẹrẹ iṣẹ awọn ọlotẹ to nko awọn Isobo ni ikọkukọ pe ki nwọn maṣe san owo asingba fun Ijọba. Alaifẹ san owo yi si farahan ni oṣu keji ọhun (*August*) nigbati adele oyibo Ajẹlẹ Warri lọ si Jeremi ati Ajayubo lati lọ la itumọ owo asingba yi ati idi rẹ ti Ijọba ṣe fẹ lati gba a.

Ni igba meji daradara ni awọn ara Ilu gbidanwo lati gba ẹniti Ijọba mu pe o nko awọn enia lati di tẹmbẹlẹkun lowọ ọlọpa silẹ. Nwọn lu ọlọpa to sin Ajẹlẹ lọ si ilu nwonyi, ati ni igba kan pẹlu awọn ọlọpa ni lati fi idi ibọn lu nwọn, ki wọn to le gba ara wọn silẹ. Eyi si di ogun ti Ijọba ni lati ran ọlọpa kun ọlọpa to sin Ajẹlẹ lọ si Jeremi ati jAayubo. Ọpọlọpọ enia to nlọ si Ipade ti ko tọ lori ọrọ yi ni Ijọba mu ti nwọn si ba ro ẹjọ. Lẹhin ti nwọn si ti ko awọn Ọlọpa kuro ni ilu wọnyi ni ọjọ kọkanla oṣu *September*, eyini ni oṣu to kọja, ko si rogbodian kan mọ, gbogbo ilu pa rọrọ.

Ni ipari oṣu *September* to kọja, adele Gomina papa fi oju ara rẹ ri iwa ati iṣesi awọn Sobo lori ọrọ owo yi. Idarudapọ lo si wa lẹhin ipade awọn Ijoye ni Warri nibiti Adele ba wọn sọrọ, ṣugbọn ko si ọrọ pe ẹnikan lu ẹnikan nibẹ. Ninu apẹrẹ miran to farahan pe Isobo ko fẹ san owo yi ni, ọja ti nwọn ko ta fun awọn oyibo onişowo mọ, ati eyiti wọn ko ra lọwọ wọn.

Ni ọgbọn ọjọ oṣu Sẹptẹmba to koja, Adele Gomina ba Ipade awọn Oloye ati Ilu sọrọ ni Sapẹli lori ọrọ owo asingba yi. Idarudapọ pupọ si wa lẹhin ipade yi ; nibiti awọn ọlọpa to ṣe pe ponpo nikan ni wọn mu dani ngbidanwo lati tu ipade ka, bẹni awọn ọlọpa mu ẹnikan ninu awọn to nle be-be nibẹ lọ si Ṣabu wọn. Ko pẹ lẹhinna nigbati Adele kuro ni Sapẹli ni ọpọ enia rọ lọ si Ṣabu ọlọpa, nwọn si bo oyibo ọlọpa, ati ọlọpa mejila, to wa nibẹ, ni kuku to dara. Nigbati igbe dun ẹlomiran ninu awọn ọlọpa nwọnyi lara, ni nwọn ni lati ranṣẹ fun ibọn ni Teṣọn ọlọpa. Lẹhin ti nwọn ti yin ibọn lẹmeji tabi lẹmẹta si ofurufu ti awọn Isobo ko sa, ni awọn ọlọpa to gba aṣẹ lati yin ibọn lu nwọn, ibọn ọlọpa pa Isobo kan ni apafọn, o si ṣe mẹta tabi mẹrin ninu wọn leṣe. Nigbana ni awọn yoku to ba ẹsẹ wọn sọrọ.

Ijọba ti fi kun ọlọpa to wa ni Sapẹli, irohin ti nwọn si gbọ lati ibẹ nisisiyi ni pe Ilu pa rọrọ bi omi amu.

O tẹ Adele Gomina lọrun lati sọ pe nigbati awọn ọlọpa sun kan ogiri ni nwọn yin ibọn, ati pe bi ko ba si ibọn ti nwọn yin na, ohun buruku miran ni iba ṣẹlẹ. Irọ ni nwọn npa nigbati nwọn ni lilu ti ọlọpa lu ẹniti nwọn mu ni ojo ọgbọn oṣu Sẹptẹmba to koja ni Sapẹli ti ṣe onikọ ika rẹ lọ si ọrun ; ọlọpa ti fi i silẹ pẹlu ara lile ati ikilọ pe wọn ko gbọdọ gbọ pe o ṣe fitafita kan mọ titi oṣu mejila."

Ẹjọ ti Ijọba fi ẹnu ara rẹ ro ni eyi fun wa ; boya ọkanna ni nwọn a ro ni Igbimọ Aṣelu, boya ọkanna ni nwọn a ro fun ọba aiye ni ilu oyinbo lọhun, boya ẹjọ kanna yi ni nwọn yio si ro fun Olodumare fun ẹjẹ ti nwọn ta silẹ bayi nitori rogbodian owo asingba, l'ọjọ Idajọ ?

Ti a ba wadi ọrọ lẹnu awọn Isobo papa, ẹjọ ti wọn le yato si eyi, bi ẹjọ awọn ara Ijẹmọ ti yatọ si eyiti Ijọba Ito wa l'Abẹokuta ro. Ṣugbọn ẹ jẹ ki a fi jigi oye wo diẹ ninu ẹjọ ti Ijọba ro, ki a si bere gbolohun ọrọ meji tabi mẹta lọwọ Ijọba.

Ekini :—Kini a ti pin itan aja ko to kan Lemọmu. Bawo ni iṣẹ alaye ọrọ ni Ipade gbogbogbo ni Sapẹl lori ọrọ owo asingba ti ṣe tọ si Adele Gomina ?

Ekeji :—Igba melo lo lọ si ipade gbogbogbo kan ni ilẹ yi ri lati sọrọ lori owo asingba yi, lẹhin ipade Igbimọ Aṣelu nibiti nwọn ti pa, ti nwọn ti kun lọna ti o lodi si ifẹ ara Ilu, gẹgẹ bi Ọlọla Dokita Jones ti sọ nibẹ ti Ọlọla Dokita Caulcrick si gbe e lẹsẹ

Ẹkẹta :—Kilo ṣe ti Adele Gomina ko lọ lati lọ la alaye ọrọ na fun wọn ni ẹgbẹ Dẹmọ ni *Glover Hall*, tabi ni ẹgbẹ awọn Dokita Randle ati Dokita Ọbasa "*The Peoples Union*" ni Ilupesi, tabi ẹgbẹ miran ?

Ẹkẹrin :—Adele Gomina ko ha mọ iru enia ti awọn Isobo jẹ pe wọn ki nfi igbagbogbo "Kọnkọ" bi awọn ara ile wa ? Awọn "*I concur, yes Sir, massah*" !

Ẹkarun :—Awọn "Ọlọtẹ" ti nwọn ni o ndi tẹmbẹlẹkun ni Warri ha daba lati ba Ijọba Gẹsi ja ogun tabi iru tẹmbẹlẹkun wo ni nwọn di ?

Ẹkẹfa :—Adele Gomina ko ba mọ pe awọn ọlọpa lo kọkọ "fa *danger*" nipa mimu ẹnikan ninu awọn to wa si ipade ni ọjọ ọgbọn oṣu Septembar ni Sapẹli, ki rukerudo to de ?

Ekeje :—Bi ẹniti ọlọpa mu na ba jẹ ọkan ninu awọn Isobo to nle bebe, ki a tilẹ wipe o nkọ awọn ara Ilu rẹ lati maṣe san owo asingba. Adele Gomina ha ro pe ko ha tọ ki nwọu ti mu ọkọnrin na siwaju ọjọ Ipade, tabi ọjọ keji lẹhin Ipade dipo eyiti nwọn mu u ni ọjọ ipade gan, mimu to da ijangbọn silẹ lẹhiuna ?

Ẹkẹjọ :—Adele Gomina ha ro pe bi awọn Isobo ba mura lati ja nitotọ, ohun ti awa mọ pe wọn ko

jẹ tabi gbọdọ ṣe nitori ifẹ nla nla ti gbogbo wa ni si aṣia Gẹsi (*God save the King*) ani, bi Isobo ba fẹ lati ja, Adele Gomina ko ha ro pe nwọn ni agbara to lati gba ibọn lọwọ gbogbo awọn ọlọpa mejila pere to mu ibọn dani, ki nwọn si bẹrẹsi fi idi ibon na ṣe awọn ọlọpa ni ṣuta? Ṣugbọn wọn ko jẹ ṣe bẹ wọn ko tilẹ si gbọdọ ṣe bẹ pẹlu!

Awa ko ro pe awọn Isobo jẹ ṣiwere de ibiti nwọn ma wipe awọn fẹ ba Ijọba ja, bi nwọn ba si fẹ gbidanwo nkan bẹ, ko si ẹnikẹni ninu gbogbo Eko, ati awa ti a nkọ iwe yi papa, ti ki yio da wọn lẹbi pupọ, nitori Ijọba Gẹsi ni awa papa nfi ori ba'lẹ fun; bi aṣoju wọn ni ilẹ yi ba si fẹ so ajaga ofinkofin ti ko wọ fun wa mọ wa lọrun, ko si ibiti a ko ni be nwọn de; ko si ibiti a ko ni lọ ibosi wọn de, ao ke titi, ao ke de ọdọ ọga wọn *Secretary of State* ni ilu oyibo, tabi Kilopo?

Ijọba fẹ ki a gbagbọ pe lẹhin ti nwọn ko ibọn de fun awọn ọlọpa lati Tẹṣon, nwọn yin ibọn na si oke lẹmeji tabi lẹmẹta; sibẹsibẹ, awọn Isobo ko tuka; a ko wipe Ijọba npurọ, ṣugbọn eyi ṣoro fun wa pupọ lati gbagbọ pe ẹni ti ko mu ibọn dani yio duro de ẹni to ni ibọn lọwọ to si ti bẹrẹsi yin si ofurufu,

Lẹhin ti nwọn yin bon si ofurufu bayi tan, tan fun wọn l'aṣẹ lẹhinna lati da oju ibọn na kọ awọn enia de ipo ti ẹnikan nku iku gbigbona larin wọn, ti ẹni mẹta tabi mẹrin si gb'ọgbẹ, gẹgẹ bi Ijọba ti wi.

Kilo njẹ "ẹni mẹta tabi mẹrin"? Ijọba ko ha mọ iye enia to gb'ọgbẹ ni, boya ti nwọn si ṣubu lu'lẹ lẹsẹkanna, de ipo ti nwọn tun nlo ọrọ "tabi"?

Dajudaju, Ijọba wa ni ipo lati mọ: o si yẹ ki nwọn mọ laisi tabitabi kan ninu rẹ, pe iye enia bayi lo "gbe'le gb'ọfa lai r'ogun."

Ẹ gbọ bi ofin ti wi nipasẹ Ipade tẹmbẹlẹkun ati ọtẹ si Ijọba:—

"A riot is an unlawful assembly which has actually begun to execute the purpose for which it assembled by a breach of the peace and to the terror of the public. A lawful assembly may become a riot if those assembled proceed to execute an unlawful purpose, and to terrorise the people, although the assembly had not that purpose when it assembled. The punishment is imprisonment with hard labour.

Wherever twelve or more persons are unlawfully and tumultuously assembled to the disturbance of the public peace, the magistrate must read a proclamation calling upon them to disperse in the King's name. This is popularly known as Reading the Riot Act. Any person obstructing the reading of this proclamation, or remaining for one hour after it has been read, is guilty of felony and liable to penal servitude for life.

If the mob is actually committing crime, it is lawful to disperse them by force without reading the Riot Act, and if in so doing any member of the mob is killed, such killing is not murder."

Nitori iru ofin bayi lo ṣe yẹ ki a gbọ t'ẹnu awọn Isobo; ṣugbọn loju ti wa, ati gẹgẹ bi a ti wi ṣiwaju, a ko ro pe Ijọba ni are lati paṣẹ pe ki ọlọpa yin'bọn.

Iru ofin bayi ko ṣai ti wa ni ọdun mẹdun sẹhin ri. Ni igba ọdun ọhun o le merinla 1714 ni ofin ti a npe ni Riot Act so ipade tẹmbẹlẹkun ati ọtẹ di ẹṣẹ nibiti enia mejila tabi jubẹ lọ ba pejọ si ti nwọn si nba alafia ilu jẹ lẹhin wakati kan ti Ṣẹrif tabi Onidajọ ba ti ka ofin na pe ki nwọn tuka l'orukọ Ọba.

A ko gbọ pe a ka iru ofin bayi fun awọn Sobo ni Sapẹli ki ọlọpa to yin'bọn, boya kẹ, ẹṣẹ wọn na lo kuku pọ tobẹ loju Ijọba ki nwọn to bẹrẹsi yin'bọn lai ka a.

Eyikeyi to wu ki o jẹ nibẹ, ofin yi wa ṣiwaju, ati ni akoko, owo omi nilẹ yi njẹsi (Water Rate agitation,) nigbati awọn Dokita Ọbasa ngun ori agba ni Ilupesi ti nwọn nkigbe "A ko gba, a ko gba," ti Ilu si wa lẹhin wọn ninu "A ko gba, a ko gba na." Sibẹsibẹ ọlọpa ko yin ẹnikẹni ni ibọn l'akoko na.

Oloye Ọbanikoro to sọ loju gbogbo enia ni Ipade gbogbogbo ti nwọn ṣe ni agbala ile iṣẹ sẹkitẹri ọba the (Secretariat) pe, kaka ki a san owo omi ki Ijọba kuku di okuta mọ on l'aiya ki nwọn ju on sinu omi ọsa, ọlọpa ko yin in ni ibọn pa.

Nigbati ọlọpa mu ọgbẹni Brimah Igbo l'oru ọganjọ nitori owo omi, ti gbogbo Ilu ṣi gangan ni owurọ ọjọ keji pe gbogbo wọn ni ki ọlọpa kuku ti mọ ile pọ pẹlu Brimah Igbo, ọlọpa ko yin ẹnikẹni ni ibọn l'ọjọ na. Ibaṣe pe Ijọba yin ibọn l'akoko na, enia melo ni iba ku l'Eko loni?

Ju gbogbo rẹ lọ, ẹbẹ ni ao bẹ Ijọba pe ki o jọwọ ṣe suru pupọ pupọ nigbati o ba nba wa lọ, papa ni igbati o ba nba Ilu bi Isobo ti ko ni anfani ilaju ti Eko ni to. Ko yẹ ki iru ọrọ owo ori bayi di oguu ibọn rara

Adura gbogbo Eko loni si ni pe ki o le wọ Ijọba lati da ọrọ owo asingba yi ro fun wa laisi ponpo ọlọpa, laisi ibọn, laisi tulasi on bilisi.

Iba ọrọ diẹ kiun ti ao sọ lori ọrọ rogbodian to wa ni ilu Sobo nisisiyi ni eyi nitori owo asingba, iyoku di ọjọ miran, ọjọ're.

Gbogbo ohun ti enia ba ṣe l'aiye yio jihin rẹ l'ọjọ Idajọ.

Abọ wa re o, ikọ o mà k'ejo l'ẹsẹ.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

## ỌJỌ-IBI KẸTA-LE-LOGOJI (43).

A ba arakọnrin wa yọ,

MR. A. ADEṢUBUỌLA

Ọkan ninu awọn Ọlọla Ilesha, fun ojọ-ibi rẹ kẹta-le-logoji (43) ti o ṣe ninu oṣu September yi.

Ọrẹ wa yi jẹ gbajumọ, oninure ati oniwapẹlẹtu enia, o si fi iwọnyi jọ baba on iya rẹ lọpọlọpọ.

A ki ọ, ọmọ "Olowo-ori-oke" o ku ayọ-ọdun to o ba ọ l'alafia, ki Ọlọrun Baba-alanu ko fi ọpọ rẹ ban ọ si. Amin.

*Oriki*:—A mọ l'ẹwa bi Ọkin, Iṣọla, Ariṣenibi Oyinbo Iwora, Ẹlẹrin-o-ṣenge, Baba Adeyinka.

Ilu baba on iya rẹ a san ọ o.

## *Thanks for Sympathy.*

Mr. Alufa Amọdu Tijani Baruwa, on behalf of himself and other members of family beg to return their sincerest thanks to all those who by personal calls, letters, telegrams, or otherwise express sympathy with them on the sad loss sustained by them in the death of their dearly beloved daughter Madam Muniratu Asule, who died at 28, Porto Novo Street, on the 26th of October, 1927.

## "The Nigerian Daily Telegraph"

It is rumoured that within a few days another Journal named as above will be added to Nigerian Journalism. The paper we understand will be edited by H. Antus Williams, Esq., late Editor-in-chief of the *Lagos Daily News*.

## "At Home" at the Glover Memorial Hall.

Mrs. C. C. Adeniyi-Jones will be "At Home" at the Glover Memorial Hall on Friday the 4th proximo at 8.45 p.m.

Programme includes Music and Dancing.

### TO OUR READERS

Our correspondent Ajagbe-Ọ̀ṣa's usual weekly Article is unfortunately crowded out of this issue due to its reaching us late.

ED. E. A.

## AJAJO ILE AIYE.

Agbẹjọro Ọba kan si Loya J. C. Zizer pe ki o wa sọ idi rẹ ti Kotu ko ni fi gba Agbada ati Fila iṣẹ rẹ, fun ẹsun kan ti aigbọ pe Agbẹjọro Ọba nfi sun nisisiyi, ni Wednesday ọsẹ to mbọ ni nwọn ma fọn si ẹjọ na ni Gauran.


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ oju-lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣọ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jọ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Şugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ẹda ati gbogbo arun ti ki ę ki ọkunrin şe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loşoşu—Işę ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not oblainable elsewhere.*

GBOGBONIŞE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fę baję, ati orişirişi arun mi ti ki ję ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S
## WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.
N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISOYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe, awọn ti o nfi iwe şişę ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer.

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy of Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILANA EJE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rę mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşę Ewurę pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ęyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oju, Ęsanri ni akoko bela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

### GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop. 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

### Indents House.

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

**A Trial is Solicited.**

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

## One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

**A. B. Williams,**
14, Bishop Street, Lagos.

## *ILE OWO OYINBO*

# JOHN RADCLIFFE

Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

——:•:——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremẹre bi Ṣẹda, aṣọ Yọmin ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ oriṣiriṣi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ loriṣiriṣi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun 'ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.